**JOINT UNIVERSITIES PRELIMINARY EXAMINATIONS BOARD**

SEPTEMBER 2020 EXAMINATIONS

JUPEB/019

**YORUBA ART – J129** **Time Allowed: 3hours**

## SECTION A: MULTIPLE CHOICE QUESTIONS

Answer all questions in this section.

Use the OMR answer sheet provided to answer the questions. Follow the instructions on the OMR sheet.

## SECTION B: ESSAY QUESTIONS

Answer FOUR questions; ONE question from each course.

**SECTION A: MULTIPLE CHOICE QUESTIONS.**

**Answer All Questions.**

1. Èwo ni àfipè àsúnsí nínú àwọn ẹ̀yà ara ìṣafọ̀ wọ̀nyí?
   A. Káà ọ̀fun.
   B. Àjà ẹnu.
   C. Erigì.
   D. Iwájú-Ahọ́n.

2. Nínú àtẹ ìró fáwẹ́lì èdè Yorùbá, /ɔ/ jẹ́ fáwẹ́lì
   A. òkè
   B. ẹ̀bákè
   C. ẹ̀bádò
   D. odò

3. Sílébù ni _______ tí èémí lè gbé jáde ní ìsẹ̀èémí kan ṣoṣo.
   A. ọ̀rọ̀.
   B. afọ̀.
   C. ègé ọ̀rọ̀.
   D. ègé iró.

4. Èwo ni apààlà sílébù fún ọ̀rọ̀ ***Àjẹkúlayé?***
   A. à, jẹ, kú, la, yé.
   B. à, jẹ, kú, ni, ayé.
   C. *j*ẹ, *k*ú, *l*a, *y*é.
   D. à, ẹ, ú, a, yé.

5. Odo sílébù ló máa ń ṣiṣẹ́ _______ fún sílébù nínú igbésẹ̀ ègé ọ̀rọ̀.
   A. pààlà láàrin ìró kọ́ńsónáńtì.
   B. ṣe iṣẹ́ sílébù.
   C. didún sílébù gan-an.
   D. sílébù nikan.

6. Èwo ni ìhun sílébù ***Àkààkààkọ́gbọ́n-ń-ròde*** nínú àwọn wọ̀nyí?
   A. FKFKFKFFFKNKF.
   B. FKFFFKNKFKNF.
   C. FKFFKFFKFKFNKFKF.
   D. FKFFKFFKKKFNKFKF.

7. Ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì tí ó wáyé nínú ọ̀rọ̀ ***àlùpàìdà*** ni
   A. fáwẹ̀lì
   B. ìpajẹ kọ́ńsónáńtì
   C. ìpajẹ ohùn
   D. ìpajẹ fáwẹ̀lì

8. Àrànmọ́ _______ wáyé nínú ***ọlọ́kọ̀***
   A. ohùn
   B. iwájú
   C. afòró
   D. aláìfòró

9. Bí fáwẹ̀lì /o/ bá jẹ́ **F1**, àwọn fáwẹ̀lì tí ó lè jẹ́ **F2** fún un nínú igbésẹ̀ ìjẹyọpọ̀ fáwẹ̀lì ni
   A. /ẹ/
   B. /ẹn/
   C. /o/
   D. /ọn/

10. Ọ̀kan lára àwọn èdè àgbáyé tí Yorùbá tí ń ṣábà yá ọ̀rọ̀ lò ni _______
    A. Gẹ̀ẹ́sì.
    B. Gíríìkì.
    C. Fulfude,
    D. Ìgalà.

11. Èwo ni àfetíyá nínú àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí?
    A. Tábìlì.
    B. Bíbélì.
    C. Tébù.
    D. Pétérù.

12. Èwo ni àfojúyá nínú àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí?
    A. Báíbù.
    B. Pọ́ọ̀lù.
    C. Ẹ́sítà.
    D. Mọ́tò.

13. Èwo nínú àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ni Ọ̀rọ̀-orúkọ ènìyàn ni?
    A. Ifátómilọ́lá.

B. Àmọ̀tẹ́kùn.
C. Ọ̀bọ.
D. Àkàlàmàgbò.

14. Èwo ni ọ̀rọ̀-orúkọ àfòyemọ̀ nínú àwọn wúnrẹ̀n ìsàlẹ̀ yìí?
A. Owó.
B. Ọ̀bọ.
C. ààńú.
D. Ààńú.

15. Iṣẹ́ tí ọ̀rọ̀-orúkọ ń ṣe nínú ìhun gbólóhùn èdè Yorùbá ni ọ̀kan nínú àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí.
A. Ẹ̀yán fún ọ̀rọ̀-ìṣe.
B. Orí fún àpólà iṣe.
C. Àbọ̀ fún ẹ̀yán.
D. Olùwà gbólóhùn.

16. Ọ̀rọ̀-orúkọ lè jẹ́
A. ọ̀rọ̀kọrọ̀ tí ó ní ìhun FKF.
B. ọ̀rọ̀kọrọ̀ tí ó ní ìhun KF.
C. ọ̀rọ̀kọrọ̀ tí ó ní ìhun KKFF.
D. ọ̀rọ̀kọrọ̀ tí ó ní ìhun KKKFKF.

17. Èwo nínú ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ èdè Yorùbá wọ̀nyí ló ń ṣe iṣẹ́ kókó-gbólóhùn?
A. Ọ̀rọ̀-ẹ̀yán.
B. Ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ.
C. Ọ̀rọ̀-àpọ́nlé.
D. Ọ̀rọ̀-ìṣe.

18. Ọ̀rọ̀-ìṣe mélòó ló wà nínú ìhun gbólóhùn ***Olówó ni ayé mọ̀****?*
A. Ọ̀kan ṣoṣo.
B. Méjì.
C. Mẹ́ta.
D. Mẹ́rin.

19. Ọ̀rọ̀-ìṣe mélòó ló wà nínú ìhun gbólóhùn Abọ́dé*?*
A. Ọ̀kan ṣoṣo.
B. Méjì.
C. Mẹ́ta.

D. Mẹ́rin.

20. Fa ìlà sí ọ̀rọ̀-ìṣe inú gbólóhùn yìí: ***Kọ́lá ni owó tí ó pọ̀.***
    A. Kọ́lá.
    B. ni.
    C. ní… pọ̀.
    D. ní… tí ó pọ̀.
21. Nínú àwọn wọ̀nyí, àpẹẹrẹ ẹ̀yán-ajórúkọ ni
    A. wọ̀nyí.
    B. yìí.
    C. àgbààyà.
    D. yẹn.

22. Ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ tó máa ń dá kún ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ nínú ìhun gbólóhùn èdè Yorùbá ni
    A. ọ̀rọ̀-àpèjúwe.
    B. ọ̀rọ̀-ìṣe.
    C. ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ.
    D. ọ̀rọ̀-atọ́kùn.

23. Tọ́ka sí èyí tí ó jẹ́ ẹ̀yán aṣòǹkà nínú ìhun gbólóhùn yìí ***Ilé mẹ́ta ni bàbá kọ́.***
    A. Ilé.
    B. mẹ́ta.
    C. ni.
    D. bàbá kọ́.

24. Abala ibo ni a ti sábà máa ń rí ọ̀rọ̀-atọ́kùn nínú ìhun gbólóhùn èdè Yorùbá?
    A. Ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn.
    B. Ààrin gbólóhùn.
    C. Òpin gbólóhùn.
    D. Ẹ̀yin àbọ̀ gbólóhùn.

25. Èwo ni wúnrẹ̀n atọ́ka fún ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-atọ́kùn èdè Yorùbá nínú àwọn wọ̀nyí?
    A. nàà.
    B. yẹn.
    C. ní.
    D. wọ̀nyí.

26. Bí ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ _______ kò sí nínú ìhun gbólóhùn, gbólóhùn náà lè ní ìtumọ̀ kíkún
    A. ọ̀rọ̀-ìṣe
    B. ọ̀rọ̀-atọ́kùn

C. ọ̀rọ̀-orúkọ
D. mẹ́tẹ̀ẹ̀ta (A), (B) àti (C) lókè

27. Ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá tí àwọn Babaláwo jẹ́ agbátẹrù rẹ̀ ni
A. ẹ̀kún iyàwó.
B. iyẹ̀rẹ̀ Ifá.
C. òkú pípè.
D. ìjálá.

28. Nínú ewì alohùn Yorùbá wo ni ìpèdè ***A dífá fún*** ti máa ń jẹ yọ?
A. òwe.
B. àlọ́ àpamọ̀.
C. ẹsẹ-Ifá.
D. dadakúàdà.

29. Àwọn oníṣẹ́ ìbílẹ̀ Yorùbá tí Ìjálá sísun jẹ lógún jù lọ ni
A. Amọ̀kòkò, Awakọ̀ àti Babaláwo.
B. Ọdẹ, Mọlémọlé àti Agégẹdú.
C. Ọdẹ, Àgbẹ̀dẹ àti Àgbẹ̀.
D. Tíṣà, Adájọ́ àti Agbejọ́rò.

30. Àwọn wo ni Iwì Egúngún jẹ lógún jù lọ nínú àwọn wọ̀nyí?
A. Awo ọpa.
B. Olórò.
C. Awo Egúgún.
D. Awo Abiamọ.

31. Ta ló máa ń sun Ẹkún Ìyàwó nínú àwọn wọ̀nyí?
A. Opó tí ọkọ rẹ̀ ṣẹ̀ṣẹ̀ kú.
B. Obìnrin tí ó dá ilémoṣú.
C. Wúńdíá tí ń re ilé ọkọ.
D. Aya tí ń bá ọkọ rẹ̀ lọ sí oko.

32. Kín ni ìwúlò Ẹkún Ìyàwó fún obìnrin tó ń sun Ẹkún Ìyàwó?
A. Èébú ṣíṣe àti ìtàpórógan.
B. Ìparí-ìjà láàrin ọkọ àti aya.
C. Ìfẹ̀míìmoorehàn àti gbígba ìre.
D. Nígbà tí obìnrin bá ń rọbí.

33. Ọnà mélòó ni Àlọ́ pípa pín sí ní àwùjọ Yorùbá?
    A. Ọ̀kan ṣoṣo.
    B. Méjì.
    C. Mẹ́ta.
    D. Mẹ́rin.

34. Parí Òwe Yorùbá yìí **Ọmọ tí à ń bá wí, tí ń warùn kì**
    A. òbí yóò fi ẹjọ́ rẹ̀ sun olùkọ́
    B. òbí kò ní ra aṣọ ọdún fún un
    C. yóò parun lójijì
    D. òbí rẹ̀ yóò kú

35. Inú Àrọ̀ jíjá ni ìpèdè
    A. kí agogo ẹnu mi ró lẹ́ẹ̀mẹta, tí ń wáyé.
    B. tótó, ó ṣe ọ̀rọ̀ àgbà o! tí ń wáyé.
    C. Mo járọ̀, mo járọ̀, tí ń wáyé.
    D. pàá pàá, ẹ máa bọ̀, tí ń wáyé.

36. Ìpèdè tó máa ń sábà ṣíde Ìmọ̀ bíbú ni
    A. ìsáǹsalùbọ̀ pẹẹrẹpẹ!
    B. ẹ má wẹ̀yìn o!
    C. ojú ẹkùn ń pọ́n, irù ẹkùn ń le!
    D. ǹjẹ́ ní mo bú mọ̀-ọ́n!

37. Èwo nínú àwọn wọ̀nyí ni kò sí nínú Orin ibílẹ̀ àwọn Yorùbá?
    A. Tàkasúfèé.
    B. Orin Ìrẹmẹlẹ́kún.
    C. Orin Ọbitun.
    D. Orin Olórogún.

38. Èwo ni ó jẹ mọ́ ẹ̀sìn ibílẹ̀ Yorùbá jù lọ nínú àwọn wọ̀nyí?
    A. Ijó bàtá.
    B. Àpàlà.
    C. Fújì.
    D. Jùjú

39. Èwo nínú àkọlé àwọn ***Àròfọ̀ Orin Ṣọ̀bọ̀ Aróbíodu*** wọ̀nyí ni ó jẹ mọ́ ìṣẹ̀lú jù lọ?
    A. 'Àwọn Oókì ṣọ̀bọ̀'.
    B. 'Àdúrà fún Gbádébọ̀ Ọba Aláké'.

C. 'Ìjọ̀ tí mo bá kú'.
D. 'Ẹni fẹ́ni'.

40. Èwo nínú àwọn àkọlé D.A Ọbasá (1982) ni ó jẹ mọ́ ìwà ọmọlúàbí jù lọ?
 A. 'Ọmọ'.
 B. 'Ọgbọ́n'.
 C. 'Ẹ̀dá'.
 D. 'Ìlara'.

41. Olú ẹ̀dá-ìtàn ìwé ***Ògbójú Ọdẹ nínú Igbó Irúnmọlẹ̀*** ni
 A. Lámọrín.
 B. Aláde-Igbó.
 C. Àkàrà Oògùn.
 D. Olórí Igbó.

42. Irúfẹ́ ọgbọ́n-ìsọ̀tàn wo ni D.O Fágúnwà lò láti gbé ìtàn inú ìwé rẹ̀ ***Ògbójú ọdẹ nínú Igbó Irúnmọlẹ̀*** **kalẹ̀?**
 A. Ojú mi ló ṣe.
 B. Orin kíkọ.
 C. Lẹ́tà kíkọ.
 D. Ewì nínú ìtàn.

43. Kín ni olú kókó-ọ̀rọ̀ ìwé ìtàn-àròsọ ***Ògbójú Ọdẹ nínú Igbó Irúnmọlẹ̀***?
 A. Olè jíjà.
 B. Ìwà ọmọlúàbí.
 C. Ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ ṣíṣe.
 D. Ìkówójọ fún ìlú.

44. Kín ni orúkọ ọ̀rẹ́ tímọ́tímọ́ Olú ẹ̀dá-ìtàn inú ìwé ìtàn-àròsọ ***Ìtàn Ìgbésí Aye Èmi Ṣẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún Ọkọ Láyé?***
 A. Abíọ́lá.
 B. Àṣàkẹ́.
 C. Àyọ̀ká.
 D. Olojò.

45. Ọgbọ́n-ìsọ̀tàn wo ni òǹkọ̀wé ***Ìtàn Ìgbésí Aye Èmi Ṣẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún Ọkọ Láyé*** fi ṣíde nínú ìwé ìtàn-àròsọ rẹ̀?
 A. Arinúróde.
 B. Ojúmilóṣe.

C. Àlá lílá.
D. Lẹ́tà kíkọ.

46. Àṣà Yorùbá wo ló jẹ yọ nínú ìbáṣepọ̀ Àgbọ̀nyín àti Ìyáalé-Orí?
A. Ọba jíjẹ àti ìgbeyàwó.
B. Òkú sísin àti ìsọmọlórúkọ.
C. Ijó jíjó àti Orin kíkọ.
D. Okòwò àti ìgbẹ̀bí.

47. Ewo Ẹ̀dá-ìtàn tí ìlú fẹ́ràn jù lọ ni nínú àwọn wọ̀nyí?
A. Gáà Ọṣọ̀run
B. Ọláyìíòtán
C. Òbé
D. Adégoólú

48. Èwo ni olólùfẹ́ Àgbọ̀nyín nínú àwọn wọ̀nyí?
A. Kúdẹfù.
B. Akínkúnmi.
C. Akíntúndé.
D. Gáà Ọṣọ̀run.

49. Ewo Olú kókó-ọ̀rọ̀ inú ìwé eré-onítàn ***Agbàlọ̀wọ̀ọmérì Baálẹ̀ Jòǹtolo*** ni nínú àwọn wọ̀nyí?
A. ìpínyà láàrin tọkọ taya
B. ìwà ìjẹgàba àwọn adarí ìlú lórí mẹ̀kúnnù
C. oyún ṣíṣẹ́
D. ogun àti ọ̀tẹ̀ láàrin orílẹ̀-èdè méjì

50. Ewo Orúkọ olú ẹ̀dá-ìtàn inú ìwé eré-onítàn ***Agbàlọ̀wọ̀ọmérì Baálẹ̀ Jòǹtolo*** ni nínú àwọn wọ̀nyí.
A. Aṣeeremáṣikà
B. Agbàlọ̀wọ̀ọmérìí
C. Moríyìíná
D. Àgbékẹ́

## SECTION B: YORÙBÁ ESSAY QUESTIONS

**Answer FOUR Questions in all; ONE from each course.**

### YOR 001: LANGUAGE I: YORÙBÁ PHONOLOGY

1.(a) Ṣe idàkọ àwọn iró kọ́ńsónáńtì èdè Yorùbá wọ̀nyí ní ìlànà IPA:

(i) /ṣ/

(ii) /p/

(iii) /y/

(iv) /j/

(v) /gb/ **[10 Marks]**

(b) Ṣe àpèjúwe ibi ìṣẹnupè àwọn iró kọ́ńsónáńtì èdè Yorùbá wọ̀nyí:

(i) /m/

(ii) /b/

(iii) /t/

(iv) /k/

(v) /d/ **[5 Marks]**

2. (a) Kín ni àránmọ̀? **[3 Marks]**

(b) Tọ́ka sí oríṣìí ẹ̀yà àránmọ̀ mẹ́rin tí o mọ̀ pẹ̀lú àpẹẹrẹ méjì fún ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn. **[12 Marks]**

### YOR 002: LANGUAGE II: YORÙBÁ GRAMMAR

3. (a) Kín ni gbólóhùn? **[1 Mark]**

(b) Oríṣìí ẹ̀yà gbólóhùn èdè Yorùbá mélòó ló wà, bí a bá lo ìlànà:

(i) Ìhun gbólóhùn

(ii) Ìlò gbólóhùn? **[14 Marks]**

4. Fún wa ní àpẹẹrẹ márùn-ún lábẹ́ ìlànà ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-orúkọ wọ̀nyí:

(i) Ìlò Àfòmọ́

(ii) Ìlò Àpètúnpè

(iii) Ìlò Àkànpọ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ **[15 Marks]**

**YOR 003: LITERATURE I: YORÙBÁ ORAL LITERATURE**

5. Ṣàlàyé àwọn ewì alohùn Yorùbá wọ̀nyí ní ṣókí:

(i) Ẹkún iyàwó

(ii) Òwe Yorùbá

(iii) Orin Ìbílẹ̀ Yorùbá **[15 Marks]**

6. Dáhùn ìbéèrè wọ̀nyí:

(i) Pa àlọ́-àpamọ̀ márùn-ún pẹ̀lú ìtumọ̀ ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn.

(ii) Ṣàlàyé nípa ohun tí àwọn Yorùbá ń pè ní Ìjálá.

(iii) Tọ́ka sí ipa márùn-ún tí ijó jíjó ń kó nínú ayẹyẹ àti ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá

**[15 Marks]**

**YOR 004: LITERATURE II: YORÙBÁ WRITTEN LITERATURE**

7. Ṣàlàyé bí àwọn kókó-ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ti jẹ yọ nínú ìwé eré-onítàn ***Agbàlọ́wọ́méri Baálẹ̀ Jòǹtolo*:**

(i) Ìwà ìlọ́nilọ́wọ́gbà

(ii) Sùúrù baba ìwà

(iii) Òfófó ṣíṣe

(iv) Ìwà Aríjẹnímádàrú

(v) Oore ṣíṣe **[15 Marks]**

8. Wo àgbékalẹ̀ D.O Fágúnwà nípa àwọn ìṣòro tí Àkàrà Oògùn dojú kọ lẹ́yìn ikú bàbá rẹ̀.

**[15 Marks]**